# AYÉ WÀ FUNRA RẸ̀ NI TABI A DÁ A?

## Gẹnẹsisi 1:1-31; 2 Peteru 3:1-14

## ẸKỌ 92 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Oluwa, iwọ ti o da ọrun on aiye, ati okun, ati ohun gbogbo ti mbẹ ninu wọn" (Iṣe Awọn Aposteli 4:24).**

### Ni Atetekọṣe

Ọrọ Ọlọrun ni iwe kan ṣoṣo ti o fi ọrọ wọnyii bẹrẹ "Li atetekọṣe," Oun nikan ni o ni ẹtọ́ lati ṣe bẹẹ nitori Ọlọrun wà nibẹ, O si sọ fun Mose, ẹni ti o kọ ọ́ silẹ. "Gbogbo iwe-mimọ́ li o ni imísi Ọlọrun" (2 Timoteu 3:16). Awọn eniyan miiran ti wọn kọ nipa iṣẹda aye, tabi ipilẹṣẹ rẹ, gba iroyin wọn lọdọ awọn oniwe miiran tabi ironu ayà wọn. Awọn oniwe miiran bẹrẹ kika akoko ni ọjọ kẹta ti a dá aye nigba ti ilẹ gbigbẹ farahan ti koriko, eweko, ati igi bẹrẹ si i hù (Gẹnẹsisi 1:9-13). Iru awọn eniyan bẹẹ a maa kọ́ ni pe n ṣe ni omi gbá karawun kan wá sori ilẹ ti gbogbo nnkan alaaye si tipa rẹ̀ jade. Wọn ko sọ ibi ti karawun naa tabi ẹmi ti n bẹ ninu rẹ̀ ti wá. Wọn ko mẹnu ba bi ilẹ ati omi naa ti ṣe wá si ayé, ṣugbọn Bibeli sọ pe Ọlọrun ni o dá wọn.

Awọn oniwe miiran tilẹ bẹrẹ ni ọjọ kẹrin, lẹyin ti a ti dá oorun (Gẹnẹsisi 1:16-19). Awọn ti n fi ẹnu lasan jẹ onimọ ijinlẹ wọnyii n kọ́ ni pe oorun jẹ ogidi okuta yiyọ́ ti o n yipo pẹlu aré kikankikan to bẹẹ ti apa kan rẹ̀ fi ya kuro. Sisare ti o sare yii ni o mu ki apa kan naa ṣupọ. Nigba ti o di tutu ti aré rẹ̀ si dinku o wá di ilẹ. Ṣugbọn awọn eniyan yii ko sọ ipilẹ oorun, ṣugbọn Bibeli sọ fun ni pe Ọlọrun wi pe, "Ki awọn imọlẹ ki o wà li ofurufu ọrun" (Gẹnẹsisi 1:14) ati pe, "Ọlọrun si dá imọlẹ nla meji; imọlẹ ti o tobi lati ṣe akoso ọsán" (Gẹnẹsisi 1:16).

Awọn miiran wà ti wọn ni ero pe n ṣe ni ẹmi kàn bẹrẹ ṣá ninu gẹdẹgẹdẹ ti o si di nnkan ẹlẹmi kekere, ti o fara jọ nnkan ẹlẹmi kekere kan ti o dabi ọ̀rá, ti o si jẹ pe kiki ninu digi ti n mu ki aworan nnkan tobi si i nikan ni a ti le ri i. Nipa iriri, awọn onimọ miiran ti fi han pe ẹmi ki idédé wà, ayafi bi o ba ti mu ẹmi miiran jade wá. Ninu Gẹnẹsisi 1:21, a ka pe: "Ọlọrun si dá erinmi nlanla ati ẹdá alãye gbogbo ti nrakò, ti omi kún fun li ọ̀pọlọpọ ni irú wọn, ati ẹiyẹ abiyẹ ni irú rẹ̀: Ọlọrun si ri pe o dara."

A ri i bayii pe, awọn onimọ kò fi ohun ṣọkan lori iṣẹdalẹ aye ati ti ẹmi. Ero wọn a maa di asan nigba ti ète miiran ba jade, awọn wọnyii naa a si tun maa di apati ati igbagbe, ṣugbọn Ọrọ Ọlọrun duro ṣinṣin. "Ọrun on aiye yio rekọja: ṣugbọn ọ̀rọ mi kì yio rekọja" (Luku 21:33).

### Ọlọrun Ṣẹda

Awọn ti n wi pe lati inu nnkan miiran ni aye ti hù jade yii ko fẹran ọrọ yii pe, "Ọlọrun ṣẹda." Wọn n fi ogo fun awọn ẹranko. Wọn n wi pe awọn nnkan ẹlẹmi ti wọn ni ọlá pupọ di bẹẹ nipa idagbasoke. Ki i ṣe kiki pe ẹkọ yii lodi si Ọrọ Ọlọrun nikan, o lodi si ẹkọ pe didá ni Ọlọrun dá aye, kò si ṣe deedee pẹlu iriri awọn onimọ miiran. Ọkunrin kan ti a n pè ni Mendel ti fihan pe ko ṣe e ṣe fun awọn ọmọ lati jogun iwa ti awọn obi wọn ti kọ́ tabi eyi ti wọn ti lọ́ ara wọn si. "Iwọ, ani iwọ nikanṣoṣo li OLUWA; iwọ ti o ti dá ọrun, ọrun awọn ọrun pẹlu gbogbo ogun wọn, aiye, ati ohun gbogbo ti mbẹ ninu rẹ̀, okun, ati ohun gbogbo ti mbẹ ninu rẹ̀, iwọ si pa gbogbo wọn mọ́ lãyè, ogun ọrun si nsìn ọ" (Nehemiah 9:6).

Itumọ ọrọ yii "ṣẹda" ni lati mú ki nnkan wà. "Ọlọrun dá ọrun on aiye." Nipa ọrọ Rẹ̀ ni wọn fi wà. Ko si ohunkohun ti o wà titi agbara Ọlọrun fi mu ki wọn wà. Itumọ dida ju ṣiṣe tabi kikọ́. Iya rẹ le wi pe oun yoo ṣe akara diẹ, ki o si kó ohun-elo sinu paanu kan ki o si pò wọn ki o si ṣu awọn akara naa. Oun ko le ṣe awọn ohun-elo naa, bi ṣuga, ẹja, ẹyin, iyẹfun ati ororo; wọn ti wà tẹlẹtẹlẹ bẹẹ. Ṣugbọn Ọlọrun dá gbogbo nnkan ti ó wà ni ọrun ati ni aye. Nigba ti baba kan ba fẹ kan ọkọ̀ fun awọn ọmọde, oun a ra pako ati iṣọ. Oun kò le ṣe nnkan wọnyii, ṣugbọn Ọlọrun dá ayé ati ohun gbogbo ti wà ninu rẹ̀ lati inu òfo. "Nipa igbagbọ́ li a mọ̀ pe a ti da aye nipa ọ̀rọ Ọlọrun; nitorina ki iṣe ohun ti o hàn li a fi dá ohun ti a nri" (Heberu 11:3). Nigba ti a ba ṣe ohun kan, lati inu ohun miiran ni a ti ṣe e, ṣugbọn bawo ni Ọlọrun ti yatọ to! Ó sọrọ ayé si wà!

### Eto Ọlọrun

Ọlọrun kò ṣe ẹda lati yẹ ẹ wo boya o dara tabi ko dara ṣugbọn O tẹlẹ ilana eto kan pato. Bi o ba ṣe pe eniyan ni Ọlọrun dá ni ọjọ kin-in-ni, ki ba ti si ounjẹ fun un lati jẹ, tabi ibugbe fun un lati gbé, ṣugbọn Ọlọrun mọ ohun ti o dara ju lọ. Bi a ti n kẹkọọ nipa iṣẹ ọwọ Ọlọrun (awọn ẹlomiran n pè e ni iṣẹda) a ri eto tabi ilana, ti Ọlọrun ṣe. A ri pe awọn nnkan keekeekee bi yinyin tilẹ ni awọ ti o lẹwa. A sọ fun ni pé ikọọkan wọn ni aworan ati awọ ti o yatọ. Wọn kò mu aworan wọnni funra wọn, ṣugbọn o fi eto Ọlọrun han. O ha ti tẹsẹ duro lati woye ẹni ti o

n mu ki awọn ẹyẹ kọrin tabi kọ́ itẹ? Ọlọrun ni O n ṣe wọnyii pẹlu. Awọn ti n wi pe lati inu nnkan miiran ni aye ti wà sọ pe awọn nnkan wọnyii kàn dédé ri bẹẹ ni, ṣugbọn Bibeli sọ fun ni pe, "Nipasẹ̀ rẹ̀ li a ti da ohun gbogbo; lẹhin rẹ̀ a ko si da ohun kan ninu ohun ti a da" (Johannu 1:3).

O ṣe imọlẹ o si paala saarin rẹ̀ ati okunkun, eyi ti i ṣe Ọsan ati Oru. Awọn kan wi pe awọn ko gba pe Ọlọrun wà, ṣugbọn wọn n pe imọlẹ ati okunkun ni orukọ ti Ọlọrun fun wọn -- Ọsan ati Oru. Ko ya ni lẹnu pe Ọlọrun wi pe imọlẹ naa dara nigba ti O ri i. Ki i ṣe pe imọlẹ n mu ki ohun gbogbo di riri nikan ṣugbọn o tun mu ki ẹmi le wà laaye pẹlu. O le ti yi apoti kan kuro ni ipò rẹ̀ ki o si ri pe koriko ti o wa labẹ rẹ̀ ti rọ, o ti di funfun o si fẹrẹ ku tan nitori ko si imọlẹ. Gbiyanju lati ro bi yoo ti ri lai si imọlẹ.

**Aṣaalẹ ati Owurọ**

Kò si eredi kankan ti a fi ni lati gbagbọ pe ọjọ kọọkan ti Ọlọrun fi ṣe ẹda awọn ohun ti ó wà ninu aye yatọ si iṣiro ọjọ kan ti i ṣe wakati mẹrinlelogun. "Iran kan lọ, iran miran si bọ̀: ṣugbọn aiye duro titi lai. Õrun pẹlu là, õrun si wọ̀, o si yara lọ si ipò rẹ̀ nitbiti o ti là" (Oniwasu 1:4, 5). Ninu 2 Peteru 3:4 a ka pe: "Ohun gbogbo nlọ bi nwọn ti wà ri lati ìgba ọjọ ìwa", eyi ni pe wakati mẹrinlelogun ti ó wà ninu ọjọ kan pẹlu.

Awọn kan ni ero pe ọjọ kọọkan ninu eyi ti a dá ayé jẹ́ ẹgbẹẹgbẹrun ọdun. A pín ọjọ kan si Ọsan ati Oru (Gẹnẹsisi 1:4, 5); gẹgẹ bi èrò wọn eyi yoo jẹ́ ọpọlọpọ ọdun ti o jẹ kiki imọlẹ ti ọpọlọpọ ọdun okunkun si tẹle e. Iru ẹkọ́ bayii ṣe le jẹ otitọ? Awọn eweko ko le wà laaye fun akoko pipẹ́ ninu okunkun. Bẹẹ si ni, lọna keji, bi a ba wi pe awọn eweko wà laaye fun ọpọlọpọ ọdun lai si awọn ẹranko ati eniyan lati jẹ wọn ati lati kapa wọn, awọn koriko i ba ti bo ayé kijikiji. I ba ṣe pe ọjọ kọọkan ti jẹ akoko ti o gùn to bẹẹ, ro bi Adamu i ba ti darugbo to nigba ti o wà ninu Ọgbà Edẹni.

**Pipin Omi Niya**

Ọlọrun pin omi niya, O fi lara rẹ̀ soke ofuurufu, O si fi lara rẹ̀ si isalẹ. Ikuuku ati awọsanma ni O fi sinu ofuurufu. Awọn odo, adagun omi ati okun ni o fi sori ilẹ. Olukuluku ni o ni ilò ti rẹ̀, lai si wọn ko si ohun ti o le wà laayè. Ni ọna iyanu Ọlọrun a maa fi oorun fa omi lati inu awọn okun. Omi naa a di ikuuku ti n wọ́ kaakiri loke ilẹ̀, Ọlọrun a si jẹ ki òjò rọ̀ lati rin ilẹ gbigbẹ. Bawo ni a ba ti ṣe maa bomi rin ilẹ bi kò ba si òjò? Bawo ni omi naa i ba si ti ṣe le pada sinu òkun bi ko ba si awọn odo? Ọlọrun dá awọn oke nla lati kó omi jọ gẹgẹ bi yinyin, O si mu ki wọn ga ki awọn odo maa ṣàn sinu okun. "Nitoripe on li o fa ikán omi ojo silẹ, ki nwọn ki o kán bi ojo ni ikuku rẹ̀. Ti awọsanma nrọ̀, ti o si nfi sẹ̀ lọpọlọpọ lori enia" (Jobu 36:27, 28).

Awọn omi kojọ pọ sinu awọn okun, iyangbẹ ilẹ si farahan nigba ti Ọlọrun paṣẹ bẹẹ. Awọn eniyan ati awọn ẹlẹgan pẹlu, si n pe omi ni Okun ati iyangbẹ ilẹ ni Ilẹ, eyi ti Ọlọrun ti pe wọn. Nigba ti a ba n ronu nipa bi ilẹ ati omi ti ṣe pataki to a n ri pe Ọlọrun ṣe imurasilẹ fun ẹda ọwọ Rẹ̀. Ki i ṣe ti ẹwà nikan, ṣugbọn ti ohun iyebiye ti Ọlọrun fi sinu ilẹ pẹlu -- awọn apata, ohun alumọni inu ilẹ, epo, eedu, ati ọgọọrọ nnkan miiran gbogbo ti a n lò lọjọọjọ. Lati inu okun a n ri iyọ̀, ohun elo ti ko-ṣee-ma-ni, ti o si niye lori fun pipa nnkan mọ́ ati fifọ nnkan. Awọn omi n fa iyatọ ninu oju ọjọ. Nibomiran a mu ki ilẹ tutu nibomiran a si mu ki ilẹ mooru, lati tù wa lara.

Awọn ti o ti kẹkọọ nipa nnkan bẹẹ sọ fun ni pe ko si ipinya ti a le ṣe laaarin omi ati ilẹ ju eyi ti Ọlọrun ti ṣe lọ. Bi o ba ṣe pe omi okun pọ ju bi o ṣe wa nisisiyii lọ, gbogbo ilẹ ni omi i ba bo mọlẹ. Bi o ba ṣe pe ilẹ pọ ju bi o ṣe wa nisisiyii lọ gbogbo aye ni i ba jẹ aṣalẹ, nitori ki ba si omi tó lati mu ilẹ tutu to fun irugbin. "Tirẹ̀ li okun, on li o si dá a: ọwọ rẹ̀ li o si dá iyangbẹ ilẹ" (Orin Dafidi 95:5).

Irugbin yọ, wọn si mu eso wa. Ọlọrun pin awọn irugbin si ọna mẹta: koriko, ewebẹ ati igi. Bi eniyan ba kẹkọọ nipa awọn irugbin, yoo ri i pe ipa mẹta wọnyii ni a pin wọn si, gẹgẹ bi Ọlọrun ti wi. Ki ni iwọ i ba fi ṣe ounjẹ bi kò ba si irúgbin?

**Ni Ofuurufu Ọrun**

Awọn ọrun nsọ̀rọ ogo Ọlọrun; ati ofurufu nfi iṣẹ ọwọ rẹ̀ han" (Orin Dafidi 19:1). Ọlọrun ṣe oorun, oṣupa ati awọn irawọ lati wulo ati lati lẹwa pẹlu. Oorun n fun ni ni ooru ati imọlẹ. Ki ba ti si igba ọyẹ́, igba ẹẹrun, igba ojo ati igba otutu lai si wọn. Nipa wọn ni a ti n ka ọsan ati oru ati ọdun pẹlu. O dá oṣupa fun akokò: õrùn mọ̀ akokò ìwọ rẹ̀" (Orin Dafidi 104:19).

**Awọn Ẹranko**

Nigba yii Ọlọrun ti pese ilẹ ati okun silẹ tan fun awọn ẹranko. Ounjẹ, omi ati aabo wa fun wọn. Ninu Gẹnẹsisi 1:21, a kà pé Ọlọrun da "ẹdá alãye gbogbo ti nrakò" lori ilẹ, ni oju-ọrun, ati ninu omi. Ọlọrun sure fun awọn ẹranko naa O si wi fun wọn pe ki wọn maa bí si i, eyi ni pe ki wọn maa ni ọmọ (Gẹnẹsisi 1:22-25), olukuluku ni iru ti rẹ̀ (ki wọn maa jọ baba ati iya wọn).

Awọn irugbin ko hù lati inu omi, bẹẹ ni awọn ẹranko kò jade lati inu irugbin, tabi ẹranko kan lati inu iru ẹranko miiran. Ọlọrun dá awọn ẹranko ẹhanna ni irú ti wọn – O dá awọn kiniun ni irú kiniun. Ọlọrun dá awọn maluu ni irú maluu – O dá maluu ni maluu -- wọn ko ti inu ẹranko miiran jade (Gẹnẹsisi 1:25).

Awọn eniyan kan n fẹ sọ fun ni pe nipa gbigbe ibi ti oju ọjọ ti yatọ awọn ẹranko maa n yipada. A mọ pe irun ajá maa n pọ̀ sii nigba otutu, ati pe ki akoko oru igba ẹẹrun to de ọpọ ninu irun naa a ti gbọ̀n danu, nitori bẹẹ irun ajá ki i fi bẹẹ pọ mọ ni akoko ẹẹrun. Ṣugbọn ṣá, ajá i baa gbé nibi ti otutu pọ̀, tabi nibi ti oorun mú, nigba gbogbo ajá ni ajá n jẹ́, ki i di ẹranko miiran.

**Iṣẹda Eniyan**

A dá eniyan ni iri ati aworan Ọlọrun. A dá a yatọ si awọn ẹranko. Erupẹ ilẹ ni Ọlọrun fi dá eniyan (Gẹnẹsisi 2:7). A sọ fun ni pe oriṣi nnkan mẹrindinlogun ni o wà ninu ara eniyan, gbogbo rẹ̀ si wà ninu erupẹ ilẹ lasan. Lẹyin ti Ọlọrun ti dá eniyan ni aworan ara Rẹ̀, O mí ẹmí iye si iho imu eniyan. "enia si di alãye ọkàn" "Emi o yìn ọ, nitori tẹ̀ru-tẹ̀ru ati tiyanu-tiyanu li a dá mi" (Orin Dafidi 139:14).

A dá eniyan ni ọna ti o yatọ si ti awọn ẹranko, nitori bẹẹ o yatọ. Awọn ti n wi pe lati inu ohun miiran ni nnkan alaaye ti wa a maa gbiyanju lati tọka si oriṣiriṣi ọna ti eniyan ati ẹranko fi jọra, ṣugbọn iyatọ wa to bẹẹ ti a le mọ iyatọ laaarin egungun, boya ti eniyan ni tabi ti ẹranko. Nipa abawọn ẹjẹ ni ara nnkan a le sọ boya ẹjẹ naa jẹ ti eniyan tabi ti ẹranko.

Eniyan yatọ si ẹranko, nitori eniyan jẹ alaaye ọkàn. Ni ayeraye yoo wa laaye titi lae, yala ninu itura ainipẹkun tabi ninu iya ainipẹkun (Johannu 5:29, Daniẹli 12:2).

**Ikilọ**

A ti kilọ fun ni pe awọn ẹlẹgan yoo wà ti yoo gba ero ti ara wọn gbọ́ (2 Peteru 3:3). Idagbasoke jẹ ẹkọ ti o n kọ ni pe lati inu ohun miiran ni nnkan alaaye ti jade wá, o jẹ ọkan ninu ero wọnni ti n ti inu eniyan wá, o si lodi si Ọrọ Ọlọrun. Idagbasoke ni o n kọ ni pe o jẹ eto ti o kan ṣẹlẹ ṣá lai si ọwọ Ẹlẹda kankan ninu rẹ̀. Awọn alaigbagbọ ko fẹ ọrọ ti a sọ ninu Bibeli – "Nwọn mõmọ ṣe aifẽmọ" (2 Peteru 3:5). Ẹ jẹ ki a kiyesi ohun ti Bibeli wi ki a má si ṣe ṣubu sọwọ eyikeyi ninu awọn ẹkọ igbalode nipa idagbasoke. Bi o ti wu ki àlàyé naa ti ba ọgbọn mu tó, o yẹ ki ẹni kọọkan gba Ọlọrun ati Bibeli gbọ́. K'Ọlọrun jẹ olõtọ, ati olukuluku enia jẹ eke" (Romu 3:4). A bá le di ododo Ọrọ naa mu gẹgẹ bi a ti fi kọ́ wa, fun ire wa ati fun ti awọn ẹlomiran pẹlu (Titu 1:9).

Ẹ jẹ ki a ranti pe ọpọ nnkan ti a n pe ni ọgbọn ijinlẹ ni a n fi eke pe bẹẹ (1 Timoteu 6:20). Eniyan ko le gba apa kan Bibeli gbọ́ ki o si tun gba apa kan ẹkọ "idagbasoke" gbọ́, bẹẹ ni a ko le dà wọ́n pọ̀. "Bi ẹnikẹni ba fi kún wọn, Ọlọrun yio fi kún awọn iyọnu ti a kọ sinu iwe yi fun u. Bi ẹnikẹni ba si mu kuro ninu ọ̀rọ iwe isọtẹlẹ yi, Ọlọrun yio si mu ipa tirẹ̀ kuro ninu iwe ìye, ati kuro ninu ilu mimọ́ nì, ati kuro ninu awọn ohun ti a kọ sinu iwe yi" (Ifihan 22:18, 19).

**AWỌN IBEERE**

1. Bawo ni Ọlọrun ṣe dá ọrun on ayé?
2. O gba Ọlọrun to akoko wo lati dá wọn ati ohun gbogbo ti o ó wà ninu wọn?
3. Ta ni ọkunrin kin-in-ni?
4. Nibo ni o ti wá?
5. Ni aworan ta ni a dá a?
6. Bawo ni eniyan ṣe yatọ si awọn ẹranko?
7. Sọ ni kukuru ohun ti ẹkọ "idagbasoke" nipa iṣẹdalẹ ayé jẹ́.
8. Ki ni ṣe ti o lodi si Bibeli?